# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

XIV NO 880 LAGOS SATURDAY AUGUST 3 - AUGUST 9 KỌBỌ MEJI (2D) 1963


# Tani Awon "Awe" Fe Fi Joba N'Ilesah?

## Awon Egba Dorikodo Lori Oba Alake

ILESHA — Awọn Yoruba ni nwọn ma npowe wipe bi ọba kan ko ba ku ọba kan ko gbọdọ jẹ, Nitotọ ni owe yi; lati ọjọ ti Ọba Adelupọ Ogunmokun ("Fi wajoye") Biladu Kẹta, Ọwa Ilesha ti waja ni awọn ọmọba ti oye Ọba na tọ si ti ndu sihin, du sọhun lati foju kan awọn Oloye afọba jẹ Ilesha pe ọrọ na ṣẹ nkan awọn o

Irohin nla kan ti a gbọ nipa awọn bi enia mẹdọgbọn ti o ndu oye na wipe (olukuluku wọn ni nwọn ti nfi iwe sọwọ si awọn oloye wọn lati pa itan bi oye na ṣe tọ si awọn. A gbọ wipe awọ meji ninu awọn ọmọba na ti o wa l'Eko ti fiwe ikọ ti nwọn ranṣẹ si Ilesha; awọn mejeji na ni Ọmọ-ọba Ade Haastrup ati Ọmọọba F. Ladejọla Ọginni ("Pro Bono") ti o nṣe iṣẹ ni hotẹli ni Okun Alasia l'Eko.

Mo gbọ wipe awọn ọmọba Arọmọlaran awọn iran Lufadejo, awọn Adeniran, awọn Ajimotokan ati awọn ẹbi Taiyero ni lati ṣe iwe gbogbo wọn wo.

Ni Abẹokuta awọn Ologboni afọbajẹ si wa lẹnu rogbodiyan ti ẹniti nwọn fẹ yan fun Ọba Alake miran. Akọwe Oniwe irohin wa ni on gbọ wipe awọn Ologboni na ti yan awọn enia lati lọ foju kan Olotu Ijọba Ipinle Iwọ-orun, Oloye Akintọla ni Ibadan nipa ọrọ na ati pe awọn kan nkunsinu wipe awọn ko fẹ ki Ọgbẹni R.A. Akinyẹmi, minisita alamojuto awọn Oloye tọwọ awọn bọ sọlọ rara.

Mo gbọ wipe ẹnu nkun ọmọ ọba Adeshina Gbadebọ purọ sugbọn awọn Ologboni si gbe tirẹ ti si apakan na, nwọn ni ile idile awọn ọba mẹrin ni awọn fẹ ki awọn afọbajẹ f'abẹ ge, ki nwọn si gbe lọ yewo lọdọ awọn babalawo gẹgẹbi aṣa ilu awọn Ẹgba ko nṣe idile meji rara.

(Wo yoku loju ewe kejọ)

## Gbajare, Baba U T C Da?

EKO—Ọmọ mi ku ya ju ọmọ mi junu lọ, ewo ni ti agbalagba onile ọlọna ti o sọnu larin igboro ilu Eko? Lati bi ọjọ melo kan sehin ni awọn ẹbi ati iyawo Ọgbẹni Telọ kan onisẹ aranṣọta ti ọpọlọpọ enia mọ orukọ adape rẹ ni BABA UTC, ṣugbọn Ọgbẹni Karimu Jibowu ni Iya ati Baba rẹ so, ti nwa kiri.

( Wo yoku loju ewe kejọ )

## Ofin Allikali Ko Wo Eko:

## Alaba Ara Eko Bo Lowo Olopa Ilorin

EKO—"Bi o ba ri aja Ewulọ ki o ma da'kọ fun un" ni ọrọ kiki ti awọn ọrẹ ara Eko kan ti orukọ rẹ njẹ John Alaba beresi fi ki fun ọran ọlọpa Ilorin ti o yọ bọ ninu rẹ ni ijẹrin ọde yi.

A gbọ wipe jẹjẹ ni ọkunrin ti nwọn npe ni Alaba na joko s'ọdẹdẹ ni owurọ ọjọ kan ni o ba ri awọn ọlọpa meji ti nwọn wọ ile tọ wa, awọn ọlọpa na fi iwe-aṣẹ kan ti Alikali kotu Ilọrin fọwọ si wipe ki nwọn lọ gbe Ọgbẹni na ni janto wa si iwaju on fun ọmọbinrin ara Ilọrin kan ti o ṣan lale.

Alaba ni ki awọn ọlọpa na ṣe on ni pẹlẹ, o si bọ si iyara, o mu fila ati ẹwu rẹ, o tẹle wọn. Teṣan awọn ọlọpa ni Oke Suna ni nwọn mu u gba, nwọn si ti Ọgbẹni na mọle nibẹ dọjọ keji.

(Wo iyoku loju ewe kẹta)


## LAGOS RACE CLUB

The postponed FIRST DAY August Race Meeting will take place on Saturday 3rd August, 1963. First Race at 3. 30 p.m.

THE EMIR OF ZARIA WILL BE GUEST OF HONOUR.

Sweepstake will be drawn on the numbers of Admission Tickets. 1st will be paid £2 10/-, 2nd £1 10/- and 3rd 10/-.

Also Two Silver Cups will be presented to the best dressed Ladies in national Costume and Western dress on the last day of this meeting.

COME ONE COME ALL

Hon. SECRETARY,
LAGOS RACE CLUB.


## Oro Olotu:

# Kini E Mba Ka..?

Lati ọjọ ti alaiye ti da aiye ni iwe irohin ti ko ipo pataki ninu awọn nkan ti a le ri ka pe nwọn jẹ ohun ilo pataki fun awọn ara ilu lọdọ awọn alakoso ijọba; iwe irohin na ni o si ndari awọn alakoso ijọba paapa ki nwọn le mọ bi ọna ti awọn ba ngba ṣe akoso ijọba awọn ba tẹ ara ilu lọrun tabi ko tẹ wọn lọrun.

(Wo iyoku lou ewe kejọ)

# Awon Ti O Pe Tafawa L'ole Fowo Tanran

IKẸJA — Adajọ Kotu awọn Ọlọpa Ikẹja, Ọgbẹni Adedapọ Aderẹmi paṣẹ fun awọn ọdaran meji kan, Adetunji Adeoye ati Ganiyu Salami ti awọn Ọlọpa mu wa si Kotu fun ẹsun wipe nwọn pe Alakoso Ijọba ilẹ Nigeria, Ọlọla Tafawa Balewa ni ole pe ki nwọn fi pọnun mẹwa mẹwa tanran tabi ki nwọn lọ si ẹwọn oṣu meji ti nwọn ko ba ri owo na san.

Adajọ na ni ki ẹnikẹta ti nwọn mu pẹlu wọn Amusa Ogunniran ma lọ nitoripe awọn ọlọpa ko ri ẹjọ pupọ to ma lẹsẹ.

Ọ'ọpa kan ti awọn ọlọpa ni on ni o wa lẹnu iṣẹ ni nwọn pe ni Kotu ki o wa sọ tẹnu rẹ O ni on wa lẹnu iṣẹ loju ọna Ikorodu ni Mushin lọjọ ti nkan yi ṣẹlẹ. Ọlọpa na ni on ṣe akiyesi bi mọto Ọlọla Tafawa Balewa ti mbọ lati Ikẹja ni awọn ọdaran na fo jade ti nwọn nkigbe OLE! OLE!! OLE!!! ni on ba gba wọn mu.

Awọn ọdaran na ni iro patapata ni ọlọpa yi pa mọ awọn, Ọgbẹni Ọlatunji Gomez, Loya agbẹjọro ti o ba wọn ṣe ẹjọ na ni ki a tilẹ wipe nitotọ ni ọlọpa yi gbọ ti awọn kẹ n lọgun OLE! OLE!! nwọn ko darukọ ẹnikan pataki, o si soro funun lati mọ awọn ti o nkigbe bayi larin ogunlọgọ ena ti nwọn duro, ti nwọn nworan lọjọ na.


**Never**

refuse a trial run before you choose a car. Let the cars speak for themselves and be scrupulously critical when looking at different models. We are convinced (from long experience) that any Mercedes-Benz will pass such an examination with top marks. Please give us the opportunity of substantiating our claim.

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

Lagos . Ibadan . Kano . Kaduna . Jos . P. Harcourt . Aba

Sub - Distributors:

ARMELS TRANSPORT LTD.

Benin City . Onitsha Aba


# Awon Ara Ilu Dahomey Se Ajodun Ominira Ilu Won

PORT-NOVO — Gbogbo awọn ara ilu Dahomey ni nwọn gba orişirişi alejo ni ijẹta lati ilu okere bi Ghana, Nigeria Ivory Coast, Niger ati Togo wa si ilu wọn lati wa ba nwọn ṣe ajọdun kẹta ti nwọn ti gba ominira ni ilu wọn na

Ajọdun ti ọdun yi dun pupọ ju, gbogbo awọn obinrin ati okunrin ara ilu na ni nwọn ṣe gudugudu meje lọjọ na, olukuluku wọn si yọ aṣọ ti o jọju sara, nwọn gba ojude alakoso ilu na ni nwọn nṣe gudugudu meje lọjọ na, olukulaku wọn si yọ aṣọ ti o jọju sara, nwọn gbojude alakoso ilu na, Ọgbẹni Hubert Maga lọ lati lọ ba a ṣe ajọyọ na. Ọgbẹni Magana si ba wọn sọrọ bi ilọsiwaju ti nlọ si.

Gbogbo awọn ikọ ti o wa lati ilu ajoji ni awọn minisita ilẹ na ṣe ni alejo pẹrẹwu. Awọn ọmọ ilewe ilu na paapa ṣe ere idaraya pẹlu awọn ṣọja ologun ilu na.

Nkan pataki ti awọn alakoso Ijọba ilu na tun ṣe fun gbogbo awọn ọmọ ilu Dahọmey ni wara (milk) ati omi aladun ti nwọn npin fun wọn lọfẹ kakiri gbogbo adugbo pataki pataki ti gbogbo rẹ si ndun yungba.

# Isele Nla Pa Enia Lana Ni Ilu Yugo-Slavia

YUGO—SLAVIA — Işẹlẹ nla kan ti o şẹ ni owurọ kutukutu ijẹjọ ni ilu awọn Oyinbo alawọfunfun kan ara Yugo-Slavia ti nwọn ngbe ni agbegbe Skoplje.

Işẹlẹ na pọ tobẹgẹ ti o jẹ wipe awọn enia ti o ku lẹsẹ kanna ju ẹgbaa enia lọ.

Awọn ti alapa ile wo lu mọlẹ, ti nwọn npọka iku, ti nwọn gbe lọ si ilẹ iwosan ju ọkẹ marun 100, 000) enia lọ. Awọn nkan dukia awọn ara ilu na ti o şegbe ko şe fẹnu sọ.

A gbọ wipe iru işẹlẹ nla bayi ti şẹ ni agbegbe Yugo-Slavia yi tipẹ, awọn Ijọba ilu na si nşe ọfọ awọn ara ilu na ti o jaiaisi nibẹ lọwọ.

Gbara ti işẹlẹ na ti şẹ ni o ti ko jinnijinni ba awọn ara ilu tọmọde tagba ti olukuku nsa kiri, ti nwọn ko mọ nkan ti nwọn le şe lati gba ẹmi wọn la.

Onirohin agbaiye ni gbogbo awọn waya ile işẹ Ijọba ilẹ Skoplje ni işẹlẹ na ja bi mubamu, ko si si nkan ti nwọn le fi ba awọn ara ilu miran sọrọ, Ile ero kan ti nwọn npe ni Hotel Macedonia wo lulẹ patapata, eyiti o ku awọn enia ti o ngbe bẹ ku, eyiti ogiri alapa bo mọlẹ lọ jantirẹrẹ.

Tọsan toru ni awọn enia fi nşişẹ lati ko awọn ti o ku ati awọn ti alapa şe leşe lọ si ile alaisan. Ẹrọ ni nwọn fi gbẹlẹ ti nwọn nko awọn oku si lati sin wọn, awọn miran daaa sun oku wọn nigbati wahala pọ fun wọn lati gbẹlẹ sin wọn.

Awọn oyinbo alanu ilu Amẹrika ti fi nkan orişirişi ranşẹ si ilu na lati fi ran wọn lọwọ.

# Ajala Se Igba Fomo Re

MUSHIN — Olukuluu enia ni nwọn nma gba adura wipe ki Olodumare Olọwa fi igba silẹ ki awọn e se igba fun ọmọ awọn!, ẹugbọn ninu ọsẹ yi ni Ọgbẹni O.a, de Ajala ti n wa ni opopo ad gbo ti nwọn npe ni Alhaji Ọtta Ọlọrunşogo, Mushin şe igba ọjọ-ibi fun awọn ọmọ rẹ meta.

Orukọ awọn ọmọ na ni Ọmọge Olubunmi Aja'a (ti o nşe işẹ nibi ti a npe ni West African Examination Council), Yẹmisi Ajala ati aburo wọn, Gbọlahan.

Gbogbo ẹsẹ awọn ijọ Şọşi St. Joseph ni Mushin ni nwọn pe sibẹ bamubamu nitori ... Ọmọge O... ba... Ajala je ọkan ninu awọn ọmọbinrin ti nwọn ... ma nşe işẹ iranlọwọ ni ... Şọşi na losose.

Ase ẹ Ọ... na dun pupọ, baba awọn ọmọ na si fi ijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn ti o wa sibẹ lọrun. Ninu awọn ti o wa sibẹ ni Ọgbẹni Şodẹinde, J. O. Ajala, Şegun Ajala, Fisher, Tucombe, Adẹgun, Ọmọge Bose Ajala, Layide Ajala, Tayọ Ajala ati ọpọlọpọ awọn miran ti ko si aye lati da orukọ wọn.

Ẹyin ọmọ Ajala ọlọjọbi, a ki yin, ẹmi a şe ọpọ rẹ o.

## Ofin Alikali Ko W'Eko: Alaba Ara Eko Bo Lowo Olopa Ilorin

Gbogbo awọn ọrẹ arakunrin na ati awọn ọmọlẹbi rẹ ni nwọn wa wo ni tesan awọn ọlọpa nibiti nwọn gbe ti mọle si.

Nigbati o dọjọ keji ti ilẹ mọ ti awọn ọlọpa nşe iwe ọkọ ti nwọn yio wọn Alaba si lati jẹ ẹjọ ẹsun rẹ ni iwaju adajọ Alikali Ilọrin ni awọn ẹbi Alaba ba wọ Şokoto, ti nwọn lọ gba lọya agbẹjọro kan fun un.

Lọya agbẹjọro na si gbe ẹjọ iwe-aşẹ ti Alikali Ilọrin ni ki nwọn wa fi mu Alaba lọ si iwaju adajọ Kotu Eko kan. lọya na sọrọ titi, o ni ofin ko si ni ilu Eko ti awọn ọlọpa Ilọrin fi le mu ẹniti o ba ngbe Eko ti o si yan awọn ara Ilọrin ni ale, nitorina ki adajọ fa iwe aşẹ Alikali na ya.

Nigbati adajọ si iwe ofin, o ti wipe nitoto ni ko si ofin ti o fun Alikali Ilorin ni agbara lati wa mu enia l Eko nitoripe o yan obinrin Ilọrin kan ni ale. Adajọ na ni ki Ọgbẹni Alaba ma lọ si ile rẹ, ofin Alikali ko wọ ilu Eko.

Irohin ti a gbọ nipa ọrọ n ni wipe Alula ara Ilọrin kan ti o ngbe Eko ni o mu orukọ John Alaba lọ si Kotu ibile Ilọrin ti o lọ fẹjọ ẹ sun wipe o yan iyawo on ti o nje Rafatu ni ale.

Ni Ilu Ilọrin enia ko gbọdọ ba aya alaya lo pọ tabi ki o gba iyawo oniyawo lai jẹ wipe o jawe fun ọkọ obinrin na.

YOUR SPECIALIST FOR ALL
BUILDING MATERIALS
BROSSETTE
(NIGERIA) LTD.
WHARF ROAD - APAPA - (NIGERIA)
P.M.B 1135 - APAPA.
At your service
- STOCK
- SPECIAL ORDERS
- TECHNICAL INFORMATIONS

Eleti-Ofe Daraba

# ELETI–OFE
(A NJU WỌN KOSE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAM
28, Kosọkọ Street, Lagos, "ELETI-ỌFẸ" LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV. NO 580 SATURDAY AUG 3 -AUGUST 9 1963

ORO OLOTU:

## Ara Eko, Eto Ilera Yi Ko Buru Ju

Lati ọjọ ti Minisita alamojuto eto ilera gbogbo ilẹ Nigeria, Dokita Moses Adekoye Majẹkodunmi ti gbe iwe eto ilera Eko jade lati bi oşu mẹta ni awa oniwe irohin Eleti-Ọfẹ ti nfi oju agba wo iwe eto na ati iru anfani nla ti o wa nibẹ fun awọn ara ilu. Ni oju ti awa, o YẸ KI A GBINYANJU LATI DAN ETO ILERA NA WO.

Bi ẹ ba şe akiyesi, ẹ o ri wipe lati ọpọlọpọ ọdun sẹhin ni ikunsinu ti wa larin awọn ara ilu Eko nipa itọju ti ko lọ gere to ninu ile iwosan ati pe ọpọlọpọ awọn dokita wa ti nwọn nşe işẹ ninu ile iwosan (hospital) na ni nwọn ko bikita lati şe itọju awọn alaisan ti nwọn nwa sọdọ wọn lojojumọ.

### Owo Ni Koko

Atako ti awọn dokita ti o ngbele şe işẹ fun ara wọn gbe ko eto ilera na ni wipe nwọn fẹ gba onjẹ lenu awọn ati pe o yẹ ki awọn ti o fẹ gbe eto na jade pe awọn si korọ ki awọn jọ roo wo.

Nwọn tun şe alaye ninu iwe ti awọn dokita na tẹ sita wipe eto iku ni eto ilera na jẹ fun awọn oşişẹ (lebira) ilu Eko nitoripe owo asansantan ni nwọn a ma san loşoşu, iyẹn ko si wipe ki baba ati iya wọn ti o ba wa ki wọn lati ilu okere ri anfani jẹ ninu eto na a fi ti nwọn ba ti nda owo-ilera oşoşu yi fun awọn obi wọn.

Lati tẹ awọn ara ilu lọrun, a gbọ wipe awọn alamojuto eto ilera ti gbe ti owo ti s'ẹgbẹkan, nwọn ni awọn yio fi eto ilera na dan ara ilu Eko wo lọfẹ fun ọdun mẹta gbako, nitorina ẹ jẹki a dan an wo, ETO ILERA YI KO BURU ju. Şugbọn a gbọ wipe awọn Olofin wa ti ni ki awọn eleto ilera na si fi iwe rẹ pamọ di gba miran. Ọrọ re o!

## Sardauna Soro S'agbon

Nina ọsẹ ti o kọja yi orişirişi ọrọ ni a gbọ lẹnu awọn alakoso Ipinlẹ ilu wa mẹtata ti nwọn wa şe ipade pajawiri kan lori ofin eto işelu gbogbogboo ti nwọn fẹ yi pada ati ofin itimọle-ma-duro-şẹjọ ti nwọn fẹ gbe jade, şugbọn eyi ti o pa bambari nibẹ ni ti Ọlọla Alhaji Ahmadu Bello, Sardauna Sokoto

## Iwe Si Olotu

### Itimole Oniho Ile KoYe Ni!

Idalu nişelu ni a ma ngbọ şugbọn bi ile aiye wa ti nlọ yi ko ye wa si; ọrọ awọn oşelu wa paapa ko ye awa ti a ran wọn lọ si ile igbimọ aşofin mọ.

Kinni o tun fa ti ofin itimọle alajalẹ ti awọn Olotu Ijọba wa fẹ gbejade lori awa ọmọluwabi? A gbọ wipe nwọn si fi iwe ofin na pamọ fun igba kan ni nwọn a tun gbe e jade.

Kinni o mba awọn minista oşelu wa lẹru ti nwọn fi nsare şe ofin ti awọn Oyinbo ko şe iru rẹ lori wa nigbati a wa labẹ wọn kiri?

Ẹnyin ara mi, şe ẹ ri oju aiye bayi? Boya eleyi le kọ awa ọmọ Yoruba lọgbọn ki a ma iru oke-ẹru ti a nlọ bi o ba di ẹbin ọla.

Mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi.

Ita Alagba, Emi,
Eko. Tawakalitu Shekoni

### Bello Ko Wa Ni 'Gan

Olotu Ijọba Ipinlẹ Ariwa Alhaji Ahmadu Bello ko wa ni 'IGAN' ninu ọrọ ti o sọ wipe awọn ara Ipinlẹ ti on şe Olotu fun ni nwọn npa ofin mọ ju awa lọ. Ko yẹ ki a ba Ọlọla Bello wi rara nitoripe awa ni a so ilẹkẹ mọ ologbo lọrun, awa ni a pe ki ahun ma yan.

Bi Sardauna Sokoto ba sọ wipe ni ọdọ wa ni awọn enia ti ko fẹ pa ofin mọ wa, o jare wa, şugbọn o gbagbe wipe ofin janduku ni ofin a-nna ni bilala igba nidi lori a jẹun ti o wu wa sinu wa.

Boya nwọn ko fi yee ni, ni isalẹ lọdọ wa nibi ni a nfẹ ofin ọmọluwabi iyẹn ni ko ye awọn ọmọ Bello ti nwọn fi fiwe sọwọ sii wipe awọn fẹ ofin maduro wọle na ni kiakia nitoripe oloju duda si ni ọpọlọpọ wọn.

Awa kişe ẹniti enia kan ni lati ma fọbọ lọ, a mọ nkan ti o yẹ wa.

Agọ Ẹgba, Emi ni,
Ebute-Metta. Sule Alabi

### Oro Olotu

tişe olori ọmọ ẹgbẹ Oşelu OLOMI ti Ipinlẹ Ariwa ti o sọ nidi ọkọ ni Ikẹja ki o to gba Kaduna lọ.

Ọlọla Sardauna ninu ọrọ rẹ ni ofin itimọle-maduro şẹjọ ti awọn fẹ şe ko nşe fun awọn ara ilu on ni Oke Ọya bikoşe awọn janduku enia ti o wa ni Ipinlẹ Ila Orun ati Iwọ Orun, Sardauna ni awọn ara ilu on gbọran si Ijọba lẹnu papọ.

Ẹnyin ara wa, Sardauna sọrọ s'agbọn! Awa Eleti-Ọfẹ ri wipe ọrọ ti Ọlọla Bello sọ wipe ko si awọn janduku enia ti ko npa ofin mọ nilu on KO MU LAKAIYE LỌWỌ RARA şugbọn awọn ọmọ ẹgbẹ oşelu ti nwọn nşe elegbe lẹhin awọn ẹgbẹ Alakukọ ati awọn ọpẹrẹ Okpara ti sọ wipe ọrọ rẹ ko mu ọgbọn oşelu lọwọ rara ko si nşe ọrọ ti o le mu irẹpọ wa fun ara ilu.

Şe ẹnyin na wa ri wipe nitotọ ni Sardauna sọrọ s'agbọn?

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## Lati Owo Ayiluka Mo ̈ ̈ ̃ Fun O

Ọgba ẹwọn ko dara lara! Mo ba Ọgbẹni akọrinta ti o njẹ Aloysius Gordon ti o yan aunti "Koforun' Ọmọgọ Keeler ni ale, ti awọn ọlọpa ilu Oyinbo ba a ṣejọ wipe o fẹ pa ọmọge na, ti adajọ si sọ s;wọn ọdun mẹtayọ... Lati ẹjọ ti awọn ti ṣe ẹjọ ra awọn lọya alanu ti ba a fẹsẹ si i, Gordon si u j a ẹjọ na, awọn adajọ kotu kotẹmilẹjọrun ni ko ma lọ.

Mo gbọ wipe awọn alamojuto ilu Amẹrika ti awọn ko fẹ awọn auunti Koforun nilu awọn nitori-na ki nwọn fa iwe-iṣẹ ti awọn ti fun awọn ọmọge meji kan ti nwọn npe ni Christine Keeler ati Mandy aveis ya, ki nwọn ma jẹki nwọn wọkọ wa ba ... awọn jẹ fun awọn rara.

Ṣe ẹnyin ara mi wa ri wipe orukọ rere dara ju ẹwa ati wura lọ.


## Jẹki owo rẹ ma dagba si larin ikore kan si ekeji ninu ile Ipamọ Owo ti Barclays

Nigbati o ba ta eso oko rẹ fi owo ti o pa si Ile Ipamọ owo. Fi sabẹ abo nitori igbati o ba nfẹ owo lati fi ra ohun ti iwọ o gbin sinu oko, ogùn ilẹdu tabi irinṣẹ. Nigbati owo rẹ ba si wà ninu ile ipamọ owo, ere a ma ti inu rẹ jade ni igba de' gbà.

### 'Ẹ FI OWO YIN PAMỌ SIBẸ'

Barclays Bank ti ṣe ọpọlọpọ aworan oni sinima ti a ti mọ dada to si nderin pani, boya ẹ ti ri wọn tẹlẹ. Eyi jamọ itan nipa awọn agbẹ mẹta ti wọn ko eso oko wọn lọsi ọja. Ẹnikọkan wọn pa owo pupọ.



Ọkan ninu agbẹ nwọnyi si nkọrin lọ sile to nk'igbe ki gbogbo enia le mọ wipe o ti di olowo. Awọn ọrẹ rẹ si nyá owo lọwọ rẹ, iyawo rẹ ko ri ohunkohun gbà rara. Agbẹ keji fi owo tirẹ pamọ si abẹ ibusùn, ṣugbọn ole kan ji diẹ lọ ninu rẹ ni alẹ, kòkoro tun jẹ iyiokù.

Agbẹ kẹta logbọn ju wọn lọ.

Gbogbo owo rẹ lo ko lọ tàrata silẹ Ipamọ Owo rẹ Barclays, ki o ba le ra ohun toba fẹ lati gbin sinu ọko ni akoko ati irinṣẹ pẹlu.

Ranti wipe, owo rẹ wà labẹ abọ ninu Barclays Bank.

BARCLAYS BANK D.C.O.

*Ile iṣẹ wọn mbẹ kakiri ni orilẹ ede yi.*



Majekodunmi Pegece !

# Alaye Eto Ilera Ti Ijọba Fe Gbe Jade Fara Eko (2)

## Nibi Ti A Ba Oro Na De

Ninu iwe wa 'Eleti-Ọfẹ" ti ọsẹ ti o koja ni n Doki a Majekodunmi tiṣe minisita alamojuto eto ilera fun Ijoba Apapọse ilẹ Nigeria pegede fuu eto ilera ti o ṣe fun awọn ara ilu Eko ati awọn oṣiṣẹ ibẹ. ṣugbọn awọn dokita oniṣegun ti o nṣe iṣẹ fun ara wọn nile tako eto na, nwọn ni owo oṣoṣu ti nwọn fe ki awọn ara Eko ati oṣiṣẹ ma san ni o ba eto na jẹ. Lẹhin eyi ni a gbọ wipe Ijoba ti fa iwe owo ti nwọn so wipe awọn yio ma gba loṣoṣu lọwọ awọn enia ti nwọn ba nfẹ lati ma jẹ anfani ile iwosan na yi, nwọn si ṣe ikede wipe ọdun mẹta ni awọn yio fi tọ ara Eko ẹnu wo lọfẹ lai gba epinni rara lọwọ ẹnikan.

### Aba F'eto

Awọn iṣoro meji pataki ni a ni lati te ni oriba ki ala ti a nla lori ọrọ yi to le jasi otitọ. Ekini, gbogbo eto iṣẹ ilera ti o wa ni Eko bayi ni o nfẹ afikun ti o gboro dada, O jẹ ohun ti gbogbo enia mọ wipe bi ọja kan ba ṣọwọn awọn alarobọ tabọ ma nsọ di ọwọn ni. Bẹ gẹgẹ ni ọrọ eto iṣẹ ilera ni ilu Eko Dipo pe ki awọn olowo ati ọlọla to pelu awọn mẹkunnu ti nwọn duro lati ri dokita; awọn saba ma nwa nkan fun awọn ti ṣẹ ti nwọn wa loju ọna ni, awọn wọnyẹn yio sii tete fun wọn ni aye lati lọ ri 'dokita' ati lati te ẹ gba iwọn iba egbogi di ti o wa ni ile iwosan Iru iwa bayi ko ṣe awọn talaka ati alaini ni anfani. Iru iwa be si ni gbogbo awọn alebu ti o wọpọ ni idi ọrọ iṣẹ ilera ati itọju awọn alaisan kakiri ibi iṣẹ ati ile-iwosan.

Ekeji ninu awọn iṣoro na jemọ ọrọ atunṣe ti afikun awọn eto iṣẹ ilera ati itoju awọn alaisan yio mu ọwọ, O dabi ẹni pe ko si afikun eyiowu ti a le ṣe ti o le mu awọn abinibi aidara bi melo kan ninu eto iṣẹ ilera ti a nl lọwọ ọwọ bayi kuro; afi bi a ba tu gbogbo irin iṣẹ alamojuto ati iṣakoso eto ilera atijọ yi palẹ; ki a tun gbogbo rẹ to, ki o ba le wulo fun eto titun yi.

AWỌN TOKAN

Awọn tani eto Ilera yi kan? eto Ijọba ni wipe eto ilera titun yi yio jẹ ọrọ kannpa fun gbogbo awọn enia ti nwọn ba fi ilu Eko ṣe ibugbe wọn, ki ṣe fun ti nwọn kan nibẹ ilu na wo lasan ni. Idi pataki wa fun Ijọba lati fi ọrọ eto ilera titun na ṣe a gbọdọ-maṣe fun gbogbo awọn enia ilu-ilu Naijiria, nitori a npe ni Federal Territory yi. Idi na si ni pe bi awọn olowo ba ti nlo owo wọn, bẹ na ni awọn talaka ti ko ri nkan jajẹ yio ma ṣe iwọn ti agbara wọn ba ka lori eto na ti gbogbo nkan yio si bọ si wẹku.

Ni afikun papa, Ijọba yio tun ṣe eto fun awọn enia ti nwọn kii gbe Eko ṣugbọn ti nwọn ma nwa si Eko nigbakugba fun iṣẹ tabi owo sise, lati jẹ ninu anfani na, bi nwọn ba gba lati da iye owo ti o yẹ ki nwọn da sinu apo Ijọba lori eto yi.

Jo gbogbo o rẹ lọ, anfani eto ilera titun yi yio tun kan awọn ẹlomiran ti ibugbe wọn ko si ni Eko ṣugbọn ti wọn ma nwa si Eko ni ẹkokan, bi nwọn ba tẹ, nipa sisan iye owo ti ofin pa laṣẹ fun wọn, lati ig a de

ALAISAN EKO

Bi-o-tilẹ-ti-jẹ wipe ọpọlọpọ awọn alaisan ni awọn ngbi-yanju lati gba itọju ni kete ti aisan ba ti kolu wọn sibẹ-sibẹ iriri wọn ni pe ki ni anfani lati ri 'dokita' titi di igba ti aisan na yio ti wọ wọn lara, ti yio si ti fi ẹmi wọn sinu ewu nlanla; tabi ti ibajẹ ti iru aisan miran tun da si wọn lara, yio ti pọ tobẹ ti o fi jẹ wipe ami ibajẹ na yio yio wa titi.

Lati ba le fun awọn mẹkunnu ni anfani pe ki nwọn le gba itọju ti alafia wọn ni Miaisi, ati ni iye owo pọọku, ni Ijọba Apapọ eriẹ-ede Naijiria ti ṣe ipinnu lati ṣe ifikun, ti o jọja lori anfani ti awọn enia ilu Eko nlo bayi nipa ọna iṣẹ ilera ati itọju awọn alaisan. Ipinnu Ijọba ni lati pin awọn anfani ti o wa fun lilo nisisiyi si wẹwẹ nipa pipese ile itọju awọn alaisan kọkan si adugbo kọkan ninu awọn adugbo pataki mọkanla ti a yin ilu Eko si fun ọrọ idibo, ki o ma ba si wipe, ẹnikẹni yio rare ki o to gba itọju.

Awọn ile-iwosan mọkọkanla wọnyi yio ma wa lẹnu iṣẹ tọsan-toru pẹlu awọn 'dokita' ati nọsi ti nwọn mọ iṣẹ wọn daju dada.

( Koiti pari )


CARSON PAINTS AND VANISHES




SOLE AGENTS:

IKORODU TRADING COMPANY
20 & 23, Balogun Street, Lagos.

# U.S. Chief Justice Tells African Audience : 'World Law Is Needed'

Addis Ababa, (Ethiopia — U.S Chief Justice Earl Warren told a capacity audience in the Haile Selassi I Theatre here that men, for their own salvation, must learn to employ law, no tarms, to settle their differences.

'When we consider the danger of international friction to day, it is as important for us to devote our great effort toward having a body of international law as it is to make improvement in our domestic law," Mr. Warren said.

More than 1,200 persons heard Mr. Warren speak Monday night at the occasion sponsored by the Haile Selassie I University. It was the highlight of the three-day visit to Ethopia of the Chief Justice and Mrs. Warren.

## World Law

Speaking on the topic WORLD RUL EOF LAW, Justice Warren told his audience that ha had just come from a world conference of lawyers in Athens, Greece, where lawyers from 105 countries were in attendance. They were prompted he said, by their belief that the greatest need of the world today is a world rule of Law.

'One of the things we are learnring is that there must be a better way than war to resolve the differences between nations,' said Mr. Warren He pointed out as evidence of that fact the Organization of America States, the Common Market, and 'The concept of African unity' which was reached at the recent African Summit Conference here.

"All of these advances have been premised of law, and nations must contiune to rely more and more on law', Mr Warren declared.

Justice Warren paid tribute to emerging Africa He said: 'Iam fortunate to be here at a time when this great section of the world has aroused itself from the isolation of centuries and has drawn aside the veil that has shielded it for so long from the eyes of the outside world.'

He said it was exciting to witness nation after nation emerge from centuries of colonialism to full independence and to their right ful place in the family of nations.

**Plushes, Velvet, Velveteen, Damask & Building Materials**

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

(63, Massey Street, Faji Market)

LAGOS, NIGERIA.

The House Where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed.

## Nigerian Blind Teacher Will Return With Own Guide Dog

LONDON—A blind Nigerian school teacher plans to return home from Egland next year-led by his own guide dog.

Mr. Philp Udofia of Ikot Inyany Eti went blind in 1957. He was already a school teacher and subsequently came to Britain to train to equip himself to return to teaching in a blind school in Lagos.

"Guide dogs give a blind person independence because he is not always able to find another person to take him about, Mr. Udofia explained. 'With a dog he can go anywhere he likes, even in the busiest cities, because the dogs are trained to guide and take care of you.

Mr. Udofia is now studyng at a blind sheool in Bristol, south west England. Children at the school play a full programme of games, including football, cricket, swimming and table tennies, despite their handicap. They also learn such trades as basket making, mat making, domestic science, music and piano turning.

## C. M. S' New Africa Secretary

LONDON—The Rev. Brian J. H. de Saram has been appointed as Africa Secretary of the Church Missionary Society from 1st September. He is taking the place of Canon J. V. Taylor, who is becoming C M S. Secretary General.

Mr. Saram, who is 50, was born in Kanday, Ceylon, and was educated at Dulwich College, London and the Royal College of Science where he took a B. Sc. degree. Until now he has been Men Candidates Secretary of the C M S.

## Hostel For Married Overseas Couples

LONDON-The Zebra House Council has just opened its second hostel for overseas married students in Camden Town, London. The hostel, which has been named Impala House, consists of two houses divided into eleven flats.

The Zebra House Council is a voluntary body which has dedicated itself to accommodating all races in friendship together. Already families from Nigeria, Uganda, Tanganyika, Kenya, India and Sudan are sharing the home

A spokesman of the Council told our correspondent that when the Zebra House hostel for unmarried overseas students is fully completed in about two months time, there will be accommodation for thirty-six students.

**BE TALLER**

Increase your Height
Details free. Add :—
C.T. Hospital, Azad Market,
Delhi 6, India.

# Dokita Ọkpara Gba Abuku Lowo Egbe Olomi

KADUNA —Ọrọ ja gi angba ọ r ọ eke jaghangba. ọrọ awọn oniwaka Imale ti nwọn ni rikiṣi pa wọn pọ ọrọ awọn oniwaka Imale ti nwọn ni rikiṣi pa wọn pọ nwọn dorẹ ko iọjọ ko to oṣu ọiẹ bajẹ ni orin igba ode isisiyi ti a le kọ fun awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ati ẹgbẹ Olotai (NPC) ẹgbẹ oṣelu ti ilu Hausa ti ọkan ninu olori awọn ọmọ ẹgbẹ na, Alhaji Abdallah, ni ẹlẹnu meji ni Dokita Michael Ọkpara, tiṣe baba ẹgbẹ awọn Alakukọ, ti o tafa soke tan ti o yọdo bori lori ọrọ ofin ihamọle ma duro rojọ ti o gbe wa ni ikọkọ siwaju awọn alakoso ipinlẹ yoku, ti o jẹki awọn ọmọ ẹhin rẹ ma wẹnu si olori ẹgbẹ awọn Sardanna Sokoto lara.

Ninu esi si idahun ọrọ igbolohun ti awọn ọpẹrẹ ọmọlẹhin Dokita Ọkpara gba Sardauna Sokoto wipe lọdọ awọn ara ipinlẹ Ila Orun ati Iwọ Orun ni iso ti orun, awọn ni janduku ti nwọn lo ofin ihamọle na fun nitoripe awọn enia ti on nṣe alakoso fun npa ofin mọ, Alhaji Abdallah ni Ọlọla Ahmadu Bello ko mọ nkankan rara nipa ete arekereke ti nwọn fi gbe ofin na wa si ipade awọn alakoso, o ni Dokita Ọkpara alara ni o gbe e wa wipe ki awọn yoku fọwọ si i.

O ni ẹniti o yẹ ki awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ, ẹgbẹ ọpẹrẹ Ọkpara ati awọn oniwe irohin doju ọrọ abuku wọn si lori ofin sọmọdẹru na ni Dokita Ọkpara, on ni agbalagba ti ko to gelete ti oonmi fin in.

---

## Gbajare' Baba U.T.C, Da ?

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

Di oni ti a nṣẹ irohin na ni ẹkunrẹrẹ, awọn ẹbi Ọgbẹni na ko ti ri oku tabi aaje rẹ ko si si ibiti nwọn ko ti waa de ni gbẹgbẹlẹ yi.

Karimu ti nwọn nwa na to ọmọ ao'n ọdun o si fi igba kan ṣiṣẹ lọdọ awọn Oyinbo Onisowo U.T.C. ni Ebingbeti, ibẹ ni nwọn ti fun ni orukọ kun orukọ rẹ. Lẹhinti o fi iṣẹ silẹ lọdọ awọn Oyinbo yi, on na wa doju kọ iṣẹ owo rẹ ti o kọ.

Ni Opopo ti a npe ni 81, Apọngbọn ni Isọlọ ni o gbe nile rẹ si, o si mọ aṣọ awọn ọmọge kan lọpọlọpọ. Awọn Mimi ti nwọn lọ kọ bi a ti nran kaba "BONFO" nilu papa nṣere lẹgbẹ tirẹ ni ti o ku sa aṣọ Kaba na bọ awọn obinrin ọlọmọge lọrun tan,

Gbogbo awọn obinrin ti nwọn lẹ gbe aṣọ ọdun Nabiyu fun un ran ni nwọn ba awọn iyawo rẹ kẹdun nigbati nwọn de ile ibiti o gbe ngbe ni Mushin ti nwọn si wa lẹnu wipe nwọn wa a kiri, sugbọn a gbọ wipe okọwe silẹ wipe wahala aiye yi lo su on boya ajule ọrun si le ṣe gba nnorina ki nwọn maṣe wahala kan lati ma wa o kiri. Lẹhin iwe ọjọbi ọmọ ọmọ rẹ ni o kọwe buruku si.

---

## Alake Tuntun

Iwe Aṣẹ de l tu ana lati Ibadan wipe ki awọn dile Larun ni Abẹokuta yan ẹniti nwọn ba fẹ fi jọba Alake wa larin ọjọ mẹrinla ni kiakia si ile iṣẹ minisita alamojuto eto awọn Oloye Ipinlẹ Iwọ Orun ki awọn le fọwọ si i nitoripe awọn ni oye kan.

## Ọrọ Olotu: KINI E MBA KA ..?

(o bẹrẹ loju ewe kinni).

Lẹhin Iwe iroh n ni ero asọrọ-ma-gbesi (redio) de ijẹn na ni iṣẹ pataki ti o nṣe fun awọn oselu ati awọn mẹkunnu ara ilu ti o yan awọn kan sipo aṣofin. Ni gbogbo ilu ti oju ba ti la, ti awọn ara ilu ati oselu ibẹ ba ti mọ pkan ti awọn nṣe, awọn ki ko yan awọn alore mejeji yi, iwe-irohin ati redio asọrọ-magbesi, kere nitoripe awọn nṣe wọn sọna, nwọn si njẹ ti awọn iranṣẹ ijọba nwọnyi R'ỌKAN GAN AN, ti nwọn ko ba ge wọn niyẹ. Atọka pataki ti nwọn jẹ fun awọn iranṣẹ ijọba(awọn minista) yi ko njẹ ki awọn na le te e kuna.

Ninu gbogbo anfani ti a la silẹ wipe iwe irohin ati redio nṣe fun awọn ara ilu ati ijọba wọn, kini o fa lalakoko ti awọn alakoso ijọba wa nṣe kiri, ti nwọn ni awọn fẹ ṣe ALATOJUBỌ ọrọ kan ti LỌYA AMOFIN kan sọ l'Eko laipẹ yi lori ofin ihamọ alapandodo ti awọn fẹ gbe jade?

Ewo ni a bọrọ ma tufun ọni? Ṣebi a fi igba kan sọ fun awọn ara ilu wa wipe ile iṣẹ redio asọrọ magbesi ti wa ni ilẹ Nigeria ko lẹgbẹ ninu a nsọ otitọ ati pe bi ọrọ ba ti ri ni nwọn yio ma gbee jade fun awọn ara ilu lati ile ero redio na?

Ṣebi a tilẹ sọ wipe ile iṣẹ redio na ko si fun awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu kan, GEDEGBE – NI-AWA - WA ni orukọ ti ile iṣẹ redio wa na njẹ? Kini wa mba awọn alakoso Ijọba wa lẹru nipa ọrọ ti nwọn sọ jade nibẹ? Awọn Yoruba atijọ ti sọrọ tan, nwọn ni ILE TI A BA FI ITỌ MỌ, IRI NI A WO O.

Kini a mba ka? Ṣebi awọn alagbara ilu kan tiṣo ja bayi lọ lana itan ni o ku ti nwọn nfi wọn pa lode oni. Adura ti awa oniwe irohin Eleti-Ọfẹ ni wipe itan rere ni ki nwọn ma pa nipa ilu wa lẹhin ọla.

Ṣugbọn bi a ko ba fẹ tan ara wa jẹ, iwadi alabosi ni iwadi ti a yan awọn kan wipe ki nwọn ṣe lori ọrọ ihamọ ti lọya amofin na sọ ninu ile iṣẹ redio wa ni ọsẹ ti o kọja. A da ni imọran fun awọn ti o ba da iwadi na silẹ, ki nwọn ko fa iwe eto iwadi na ya, ọrọkọrọ ni, ki a ma si gbọ iru rẹ mọ ti a ba nfẹ fi apẹrẹ iwa otitọ han. Tabi a le sọ otitọ ki a ku sibẹ? Ki a ma ni?

## Omo Nibi Niran Ku Ṣodo Tori Kobo

FREETOWN— Awọn Yoruba ni ayọ ni pa'nia, bi ko ba jẹbẹ kini o fa ọmọ ti nwọn bi nile lọna de ibi a nwe, a nlọ mokun mu kọbọ nisalẹ odo? Iru iku afọwọfa bayi ni o pa ọmọ Eko kan Ọgbẹni S L Aka ọmọ Bishorun ni ebute ọkọ elefin ni Saro (Sierra Leone) ni ijẹjọ nigbati ọ nwọkọ lati ilu Oyinbo bọ wa sile.

Ologbe na Aka - Bashọrun jẹ ọkan ninu awọn ọmọ ilẹ Nigeria ti o ti lọ kọṣẹ nilu Oyinbo ti o wa ba ọkọ oju omi kan ti nwọn npe ni ACCRA bọ wa sile, Ọlọla Fada hunsi, Gomina Ipinlẹ Iwọ-Orun paapa wa ninu awọn Ero ọkọ ti wọn bọ wa sile. Nigbati nwọn de Freetown ni Ọdọmọkunrin na ri awọn kan ti nwọn nṣe e idije TANI-LESE EMI-LESE, ti nwọn bọ somi, ti nwọn nmokun lọ si isalẹ Odo lati ma kọbọ kọbọ ti awọn ero ọkọ na nju somi. Ọmọ nibi niran yi ni on na a ba wọn d'anra wo, ibẹ ni o gba dọrun alakeji. Nwọn ti ri oku rẹ gbe ni ọjọ keji.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosọkọ Street, Lagos, Box 467
Phone 23370; Editor: (Olotu) Ọla. Ọnatade, 15 Kosọkọ Street, Lagos